# Ṣé O Ti Ṣetán fún Ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò SNAP Rẹ?

Nígbà tí o bá bẹ̀wẹ̀ fún àwọn ànfàànì Ètò Ìrànlọ́wọ́ Àfikún Onjẹ (SNAP), ní ọ̀pọ̀ ìgbà a gbọ́dọ̀ parí ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò kan pẹ̀lú akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ ètò ànfàànì (BPS) kan. Ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò yìí jẹ́ àwòrán ránpẹ́ nípa ipò ìdílé rẹ láti mọ ìsàmúyẹ fún àwọn ànfàànì SNAP. A nílò ìrànlọ́wọ́ rẹ láti tan ìmọ́lẹ̀ sí àlàyé lórí ìbẹ̀wẹ̀ SNAP rẹ. Ro ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò náà gẹ́gẹ́ bí ọ̀rọ̀ àṣírí pẹ̀lú BPS náà nípa ipò ìdílé rẹ. Ìlépa ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò náà ni láti ṣe àkọsílẹ̀ ipò rẹ kedere, kí a lè parí ìbẹ̀wẹ̀ SNAP rẹ láì fi falẹ̀.

**Ibo ni ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò náà yóò ti wáyé?**
Ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò náà lè wáyé nípasẹ̀ ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ tàbí lójúkoojú pẹ̀lú òṣìṣẹ́ ẹ̀ka àwọn iṣẹ́ ìtọ́jú àwùjọ ní agbègbè rẹ. Àjọ ìbílẹ̀ náà yóò ṣètò àkókò kan yóò sì pèsè lẹ́tà kan tí ó ní àwọn àlàyé nípa àkókò tí a yàn, bíi déètì àti àkókò.

**Kínni a ó béèrè ní àkókò ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò SNAP náà?**
O lè máa retí láti dáhùn àwọn ìbéèrè lórí ìbẹ̀wẹ̀ SNAP rẹ, bíi:

- Kínni ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ orúkọ àti ọjọ́ ìbí rẹ?
- Kínni nọ́mbà Ìtọ́jú Ará Ìlú rẹ?
- Ibo ni o ngbé? (O lè yẹ tí o kò bá nílé tàbí tí ò bá ngbé lọ́dọ̀ mọ̀lẹ́bí/àwọn ọ̀rẹ́.)
- Ṣé ọmọ orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà ni ọ́? (Àwọn tí kìí ṣe ọmọ orílẹ̀-èdè ṣì lè yẹ.)
- Kínni iye owó tí o npa wọlé ní oṣooṣù?
- Ṣé o ní irú àkántì ilé ìfowópamọ́ kankan?
- Báwo ni o ti nmú kí ilé rẹ móoru tàbí tutù, ṣé o sì nsan owó fún ìkankan?
- Ṣé o máa nsan owó ìyálégbé tàbí owó ilé tí o rà tàbí ti àwọn ohun èlò bíi iná mànàmáná, gáàsì, omi tàbí ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀?
- Ṣé o máa nsan owó ibi ìtọ́jú ọmọ?
- Ṣé o máa nsan àwọn owó ìṣègùn?

**Kínni mo nílò fún ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò SNAP náà?**
O lè ṣa àwọn ìwé yìí jọ o máa nílò láti dáhùn àwọn ìbéèrè náà pẹ̀lú ìrọ̀rùn àti ní ọ̀nà tí ó tọ́:

- Káàdì Ìtọ́jú Ará Ìlú tí o kò bá mọ nọ́mbà rẹ sórí.
- Àwọn àkékù ìwé ìsanwó, àwọn lẹ́tà ìfúnni ní ànfàànì (bí àwọn ti Ìtọ́jú Ará Ìlú tàbí Ìṣàkóso Àwọn Ajagunfẹ̀yìntì), àwọn àkọsílẹ̀ owó ìfẹ̀yìntì, àwọn àkọsílẹ̀ iṣẹ́ ara-ẹni, àwọn àkọsílẹ̀ owó ìrànwọ́ ọmọdé, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.
- Ìfiyáni, àkọsílẹ̀ owó ilé rírà tàbí ìwé sísan owó ìyálégbé.
- Àlàyé ilé ìfowópamọ́ fún àwọn àkántì oní ṣẹ́ẹ̀kì, onípamọ́ àti àjọ ayánilówó.
- Ìwé owó ohun èlò fún gáàsì, iná mànàmáná tàbí omi.
- Ẹ̀rí ìdánimọ̀. Tí ó lè kan:
    - Ìwé ẹ̀rí ọjọ́ ìbí.
    - Ìwé àṣẹ ìrìnnà awakọ̀.
    - Káàdì Ìtọ́jú Ará Ìlú.
    - Ìwé ìyọ̀nda ìwọ̀lú tàbí ìjádelọ.
    - Ìwé ìgbélùú ti iṣẹ́.

- Káàdì tí àjèjì fi ngbé ìlú.
- Àkékù ìwé ìsanwó.

**Báwo ni mo ti lè gbáradì fún ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò SNAP mi?**

- Múra láti dáhùn, lẹ́ẹ̀kan síi, gbogbo àwọn ìbéèrè orí ibẹ̀wẹ̀ SNAP. Olùfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò náà yóò máa tẹ àlàyé rẹ sínú ẹ̀rọ VDSS, títí kan àwọn ìbéèrè tí o ti lè fò tàbí dáhùn ní ọ̀nà tí kò tọ́ lórí ibẹ̀wẹ̀ náà.
- Múra láti pèsè ẹ̀rí iye owó tí ó nwọlé, àwọn ohun èlò àti ìnáwó tí o jábọ̀ nínú ìwáàyè rẹ. Olùfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò náà yóò jẹ́ kí o mọ ohun tí o nílò láti pèsè ní àkókò ìfọ̀rọ̀wánilẹnuwò náà yóò sì kọ ọ́ fún ọ.
- Múra láti dáhùn gbogbo àwọn ìbéèrè orí ibẹ̀wẹ̀ SNAP fún ẹnìkọ̀ọ̀kan nínú ìdílé rẹ. Ìfọ̀rọwánilẹ́nuwò náà ni yóò sọ ohun tí àwọn ànfààní yín jẹ́ fún gbogbo ẹni tó wà nínú ílé SNAP rẹ.
- Múra láti dáhùn àwọn ìbéèrè nípa àwọn ẹlòmíràn tí ó ngbé nínu ílé pẹ̀lú rẹ tí kò bẹ̀wẹ̀ fún SNAP.

Lo kóòdù àwòrán QR láti rí àlàyé síi nípa àwọn ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò SNAP.

Àwòrán ìdánimọ̀ VDSS